AWON EGBE AFENIFERE NSEGUN KAKIRI ILU

# IROHIN YORUBA

Ęsin Oro Wa— "IWAJU L'ỌPA ĘBITI NRE SI"

### Akiyesi

A fẹ ki awọn onibara wa ma san owo si apo wa dede, ęnit ko ba san owo tirę, ki o ma a ya a lęnu bi a ba da a duro lojiji, ao si gba owo wa lọwọ rę

OLOTU
IROHIN YORUBA

ỌMỌ OGBOMỌSỌ SE AJỌYỌ OMINIRA :OLUBADAN YIO PADA SI AIYE RE LAIPE

VOL, IV No 684 IBADAN, MONDAY, SEPTEMBER 24, 1951, OWO IWE IROHIN YORUBA — KỌBỌ KAN (1d)

## Awon Egbe "Action Group" Nsegun

Ninu idibo keji ti awọn tun ṣe lati wọ Igbimọ Apero Ibadan (Western House of Assembly) awọn enia ti o wọle pupọ ni awọn Aṣoju ti awọn Ęgbę Action Group yan sode lati dibo fun.

Kakiri gbogbo ilu ti o wa ni Iwọ-orun Nigeria ni awọn Ęgbę Action Group m'oke daada. Nwọn ko gba awọn Ęgbę N C N C laye rara. Ọgbęni Ọbafęmi Awolọwọ ti iṣe Olori Ęgbę Action Group wọle ni Ikęnnę (Ijębu Rẹmọ), Oloye Bọde Thomas Balogun Ọyọ wọle ni Ọyọ, Ọgbęni Lọya S L Akintọla wọle ni Ogbomọshọ ati ọpọlọpọ awọn Ęgbę "Action Group" ni o wọle kakiri ilu, ṣugbọn ko si aye lati maa darukọ gbogbo wọn tabi lati fi aworan gbogbo wọn han tan.

### ỌGBẸNI J. A. ADEKỌLA BẸ EKO WO

EKO—Ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kọkondinlogbọn oṣu to koja lọ yi ni Ọgbęni J. A. Adekọla ti Kumasi de si ilu Eko lẹhin ti o ti rin irin ajo lọ si Ogbomọṣọ. O bẹ ile iṣẹ Service Press Limited wo. Inu Ọgbęni Y. Ayinla Disu ọkan ninu awọn oṣiṣẹ bẹ si dun pupọ to bẹ gẹ ẹ ti o fi mu u yika gbogbo iṣẹ na,

Arinrinajo na sọ pe on ti wa si ile iṣẹ Service Press Ltd. ni ọdun diẹ ṣẹhin, inu ohun si dun pupọ lati ri ọpọlọpọ ilọsiwaju ile iṣẹ na O si sọ pe on fẹ ki ile-iṣẹ na si lọsiwaju jubẹ lọ laipẹ ọjọ. O wọkọ pada lọ si Kumasi lọjọ kan na.



Loya Obafemi Awolowo
Baba Ęgbė "Action Group" O wọle ni Ikenne.



Loya S. L. Akintola
O wọle ni Ogbomọshọ

## Omo Ogbomoso Se Ajoyo

ZARIA,— Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu kẹjọ ọdun yi ni awọn ara Ogbomọṣhọ parapọ ṣe ajọyọ ti Ominira ilu nwọn. Nigbati o to dede agogo meje-abọ, ẹṣẹ awọn sanmọri sanmọri pejọ sile Alhaji Tijani, gbogbo ọmọ Ogbomọshọ parapọ ati agba ati ọmọde. Nigbati o to dede agogo mejila, awọn ọmọ iya wọn to wa ni Sabongeri ti o jina ni ibusọ marun nwọn de si ọdọ nwọn. Mọto meji ni nwọn gba wa pẹlu. Nigbati o to dede agogo kan ni gbogbo ara Ogbomọshọ lọ si ile Alhaji Bello nibiti nwọn pese onjẹ si. Nigbati nwọn jẹun tan ni nwọn ba tun bẹrẹ si mu ọti, ki a ma tun sọrọ siga mọ.

Ęniti o kọkọ sọrọ ni Baba Jinadu ṣe adura pe ki Oluwa Olodumare jẹki ilu wọn lọsiwaju ju bay lọ o, o si tun ṣe ọpọlọpọ alaye. Ęniti o tun sọrọ ṣe ikeji ni Alufa Amadu Ajao o sọ nipa ati ran awọn ọmọ nwọn lọ si ile ẹkọ ni Sabongeri Zaria. Lẹṣẹkanna ni Ọgbęni O. Oyewọle wipe lagbara Ọlọrun o dun ma awọn aye si wa pẹlu Lẹṣẹkanna ni Ọgbęni Ogunmọl gbe e lẹsẹ, Nigbati o to dede agogo mẹta ni nwọn ba nṣere.

A dupẹ lọwọ awọn aṣoju awọn bi S. Awoniyi, S. Ajala aṣoju Iwe Irohin Yoruba, J. Akanbi, S. Agba je a ko ni ṣai darukọ awọn bi awọn Ọgbęni Yesufu Bamidele, J. Ajan J. Adedokun, D. A, Ogunmọla, J. A. Jackson, E. A, Dada, B A Amale, G. A Ajao, Garuba Ajala S. Alapo, Alhaji Sulemonu, Yesufu Okę. Ipade na pari ni agogo mẹfa irọlẹ,

Ki Ọlọrun Olodumare ki O jẹki iru Ipade bẹ ma kari gbogbo wa Amin.

### GOMINA FO LỌ SI ILE

Ọlọla John Stuart Mrcpherson G, C. M. G. Gomina Nigeria ba ọkọ ofurufu lọ si ile leti lọ lo isinmi rẹ ni Ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi.

Ọgbęni A. E T. Benson Aṣoju Ijọba (Chief Secretary to the Government) ni o wa ni aye Gomina na nisisiyi lati ma a moju to gbogbo ọran ti o ba kan Ijọba titi yio fi de.

Ę ma a ka iwe
**Irohin Yoruba**
nigbagbogbo fun oriṣiriṣi irohin,

## Olubadan Yio Pada Si Aiye Re

Ọlọla Ajẹlẹ Agba (Chief Commissioner) fun gbogbo agbegbe Iwọ-orun Nigeria gba gbogbo eto ti awọn Igbimọ Atunluṣe Ibadan (Ibadan Reform Committee) fi si iwaju rẹ nipa ọna ti nwọn a fi maa tun ṣe Ijọba Ibilẹ Ibadan ti ko tun fi ni i si ede aiyede mọ.

Nwọn si fi sinu eto titun na pe awọn fẹ ti Ijọba ba gba eto na ki o jẹ Olubadan ni yio jẹ Alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ibadan na

Ajẹlẹ agba na si sọ fun wọn pe gbogbo eto titun na ti nwọn gbero nipa Ijọba Ibilẹ Ibadan na ni Ijọba fọwọ si ati pe ẹsẹkẹsẹ ti eto titun na ba si ti bẹrẹ ni Olubadan yio ti bọ si aye rẹ pada, O ni on si rope ki oṣu kẹwa ọdun yi o to pari gbogbo rẹ a ti bọ si.



Oloye Bode Thomas
Balogun Ọyọ
O wọle ni Ọyọ

OWE: ĘNITI O YO KI O MA YO JU, ĘNITI EBI NPA KI O MA B'ARAJĘ

# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## A KO NI IBUGBE LAIYE, ORUN NILE

Olotu, ẹ jowọ ẹ gba mi laye diẹ, ki n'le la ọrọ diẹ ye Ọgbẹni E. K. Akinlade Ilaro nipa ọrọ rẹ ti o jade ni 25 6 51 ti o sọ wipe "Ile aiye ni ile enia." Mo fẹ ki E. K. Akinlade ki o ma ka Bibeli rẹ dada ki o si ma lọ si ọdọ awọn Onitumọ ododo. Nitori itumọ ti o tumọ fun awọn ẹsẹ Iwe ti o fi sọrọ ko ba ara wọn mu rara o. Mo fẹ ki o mọ wipe a ko ni ibugbe ni aiye yi rara o. Mo si fẹ ki o mọ daju pe alejo ni wa laiye yi o. Wo Heberu 11 13-16 ati wipe Jesu l'nu ọrọ Rẹ paapa sọ pe "Ẹniti o ba sọ ẹmi rẹ nu ni aiye yi yio ri gba ni ọrun" Eyi nfi han wa wipe ao kuro ni aiye ati wipe ni ọrun ni ao gbe ṣe idajọ, ki i ṣe ni aiye yi rara o. Wo St John 12. 25.

Lotọ ni Jesu sọ fun wa pe ki a man gbadura si Baba wa ti mbẹ li ọrun nitori igbati ao ba de ọrun ni, ki Ọlọrun ba le wi fun wa wipe "O ṣeun, iwọ ọmọdọ rere bọ sinu ayọ Oluwa rẹ." Nitori idi eyi ni ohun ti Jesu nsọ (Matt. 13, 26-50; Matt 25. 21.) Mo fẹ ṣe alaye kan fun ẹ nipa ọrọ na, ni pe oko Ọlọrun ni aiye, awa enia inu rẹ ni ohun ọgbin, Ni ọjọ ikẹhin ni yio si ran Angẹli Rẹ lati kore aiye. Wo orin 580 Baptist, ọrun nile wo Oniwasu 9. 9-10 nitori mo fẹ ki o ṣe akiyesi lori ọrọ yi dada. Ki ṣe wipe wiwa si aiye ti Jesu yio tun wa lati ṣe idajọ ara ye ninu aiye kọ bikoṣe lati ko wa lọ si ọrun ni. Wo St John 3. 17 ati wipe nibo ni awọn oku ti o ti ku ngbe? Mo dupẹ lọwọ yin o Olotu, ajinde ara yio ma jẹ o.

Emi ni
J. Ọlorun Nimbẹ
AKIM ODA GOLD COAST

## Ẹ LA EYI YE MI

Inu mi a dun pupọ ti Olotu ba le tete tẹ ibere mi yi jade fun awọn ọlọgbọn bi Evangelist Akinde, Idowu Adhiterere, Omicau Alice Jokotade, Ogbojo Ode loke Amilaala, Arẹmu Erin ati ọpọlọpọ awọn ti ko si aye fun lati darukọ wọn tan.

Ibere mi na pọ diẹ, ṣugbọn mo ro pe ẹ o mu suru lati la gbogbo rẹ ye mi pẹlu ede Yoruba ti o ye kooro. Kini itumọ:- (1) Iku, (2) Isa-oku, (3) Ijika isa-oku (4) Eṣu (5) Angẹli Eṣu (6) Ina ọrun apadi (7) Ọba na ati ọmọ rẹ (8) Ilu ọrun rere (9) Ogo ilu na (10) Ibi ti mbẹ laiye (11) Ire ti mbẹ laiye ati (12) Ọmọ enia?

Abọ mi re o.

Emi ni
Ọlatunde Bamgboṣe
EKO.

## KINI ṢB TI EYI FI RI BẸ?

Olotu/Gba mi laye diẹ lati bere ọrọ yi lọwọ awọn ọlọgbọn ati ọmaran ile aiye:-

Ekin :- Opọlọpọ igba ti ẹnikan ba ti ku awọn ẹlomiran a ma a wipe awọn pade rẹ ni ọna oko tabi lẹhin odi, awọn miran a si sọpe awọn ri i dajudaju, ati pe o tun ran awọn ni iṣẹ si ile, o titọ ha ni eyi bi?

Ekeji:- Nigbamiran wọn a ma a sọ pe enia ku ni ọjọ aipe, ọna wo la gba fi mọ eyi nigbati o ṣe pe a ko mọ akoko ti ẹlẹda onikaluku da fun u ki a to kuro ni ajule ọrun?

Ẹkẹta:-Ni aiye atijọ nigbati awọn enia ko ti laju, ti wọn ko ti mọ iwe, ti wọn ko ti maa kirun tabi maa gbagbọ ole, ọdalẹ, eke, ofofo, ṣina, kẹnimani, alaparutu, onijibiti ati iru iwa buburu bẹẹbẹ miran ko pọ ni aiye, ṣugbọn nisisiyi ti aiye di aiye ọlaju ti ẹlomiran si mọ ọran titi ti o fẹrẹ le mọ oyun igbin ninu ikarahun, ti ẹsin Ọlọrun si ngbilẹ siwaju si, kini o wa faa ti awọn iwa buburu ti mo darukọ loke yi ati omiran ti nko le ma a darukọ fi npọ si lojojumọ?

Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi yio.

Emi ni
Joseph A Orukọtan
YELWA LỌNA ZUNGERU




ABIYAMỌ ETI RẸ MELO!

Abiku ọmọ nda ọ l'amu bi?
Awọn arun wọnyi ha ayọ ọmọ rẹ lẹnu bi?

AIPERI
ỌRẸRẸ
INU-IWỌ
OSI
IGBONA
IKỌ
IGBẸ-ỌRIN
OTUTU
IBA
JẸDIJẸDI

ati oriṣiriṣi awọn arun miran ti ima yọ ọmọde l'ẹnu ni igba EHIN HIHU. Lọ ra 'YARO' awo igba arun ọmọde ni fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọde l'ẹnu.

"YARO" ko pe meji ni gbogbo ilẹ Nigeria.

Ki iwọ ki o ri i pe orukọ 'YARO' ni o wa lara igo na ki a ma ba ta adamọdi egbogi miran fun

# J. A. Ajao & Brothers

GENERAL MERCHANTS

A nta awọn nkan wọnyi— Iṣana oriṣiriṣi (Matches), Oogun Iyagbẹ, (Epsom Salt), Kafura Pẹlẹbẹ (Camphor), Atike (Face Powder), Ọti Didun (Mineral Water), Cement, Bata Funfun (White Canvas Shoes) Leather Shoes (oriṣiriṣi), Beer, Shnapps. Gin, Wine, Brandy.

## Medicine Stores

A tun nta awọn oriṣiriṣi ògun ini oke Ṣọbu wa — Oogun Narun Iba, Atun-ẹiẹ-ṣe, Ikọ, Jẹdi-jẹdi, ati ògun fun Obinrin ati Ọkunrin Lakuregbe, Ehin Ọmọde.

## Abiyamo! "Bamwo" De!! Alajela Omode!!!




Idẹra ati alafia de! Ko si ibanujẹ ati aisun mọ. Angẹli olutọju ọmọ rẹ ti mu ẹbun kan wa fun u lati ọrun wa "BAMWO" ni orukọ ẹbun na. O dara pupọ fun Inu-iwọ, Iso tabi Igufẹ, Iba, Igbona, Eyi, Ailesun, Ibinu-sodi ati oriṣiriṣi aisan miran ti o ma nṣe ọmọde lakoko ehin hihu. Dan igo kan wo, iwọ yio si ri pe o dara ju eyikeyi ninu awọn ogun ti o ti nlo fun ọmọ rẹ lọ. Igo kekere 2s. 6d igo nla 4s. 6d. ọkọ 1/-.

## The

## Egba Trading Aradan Stores.

144, Denton Street, 18 Denton Bridge Street, P. O. Box 2, Ebute-Metta, Phone 569. A tun wa ni New Motor Park Ogunpa Ibadan.

# O Nwo Iko San L'ogan!




Bi idan ni VENO'S COUGH MIXTURE yi ma a wo ikọ san, a si tun ma a ko gbogbo idọti ti i ma a dun enia ni ọna-ọfun, ni aiya ati ni ẹdọ kuro, O si ti han si gbogbo aiye pe ogun iwosan ti ki I ba a ti ni fun oriṣiriṣi ikọ aiya didun ati otutu (Coughs, Colds, Bronchitis, Catarrh, Catarrhal Asthma, Night Coughs, Children's Coughs).

Kọ tete ra igo kan, dan an wo na!

VENO'S LIGHTNING COUGH MIXTURE

